# Àwọn ẹtọ àti Àwọn ojúṣe rẹ Nígbà tí O Gba Àwọn Iṣẹ́ tí a fúnni nípasẹ Ìṣàkóso Àtìlẹyìn Ìgbà pípẹ àti ojọ ogbó àti Ìṣàkóso Àìlera Ìdàgbàsókè

**Your Rights and Responsibilities When You Receive Services Offered by Aging and Long-Term Support Administration and Developmental Disabilities Administration**

Washington State Department of Social & Health Services
*Transforming lives*

| ORÚKỌ ONÍBÀÁRÀ |
|---|
| NỌ́MBÀ ÌDÁNIMỌ̀ ACES |

## Àwọn Iṣẹ́ Tó Wà Nílẹ̀

O ní ẹ̀tọ́ láti yàn nínú àwọn iṣẹ́ tí o lẹ́tọ̀ọ́ láti gbà. Bí o bá fẹ́ ni àwọn iṣẹ́. Àwọn Iṣẹ́ tí Ìṣàkóso Àtìlẹ́yìn Arúgbó àti Ọlọ́jọ́ Pípẹ́ (ALTSA) àti Ìṣàkóso Ìdàgbà Abarapá (DDA) le sanwó fún le má ràn ọ́ lọ́wọ́ pẹ̀lú gbogbo ohun tí o nilò.

ALTSA àti DDA ń pèsè àwọn iṣẹ́ nínú:

- Ilé Ẹbí Àgbà kan, Ohun Èlò Ìrànlọ́wọ́ Ìgbé Ayé, Ohun Èlò Àwọn Iṣẹ́ Ìmúgbòrò, Ohun Èlò Ìtọ́jú, Ilé Alájọgbé, Ilé Ọmọ Aláìlóbìí, Ilé Ìgbé Òṣìṣẹ́ Ọmọdé tó Gbàṣẹ; Àwọn Ilé Ẹgbẹ́ DDA, Àwọn Ilé Ìkẹ́kọ̀ọ́ Ẹgbẹ́, ICF/Àwọn ID; TÀBÍ
- Ilé àdáni ẹnìkan. **Àkíyèsí:** ALTSA àti DDA kò pèsè wákàtí 24 lójúmọ́ tí a sanwó fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú nínú ilé àdáni ẹnìkan. Tí o bá fẹ́ ìtọ́jú wákàtí 24 a le ro àwọn àṣàyan iṣẹ́ míràn.

Adarí Ẹjọ́ AAA Rẹ, Adarí Ohun Àmúlo Ẹjọ́ DDA, tàbí Akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ Iṣẹ́ Ìgbàlódé HCS ni a pè ní **òṣìṣẹ́ ẹjọ́** nínú àkọsílẹ̀ yìí.

## Àwọn Ẹ̀tọ́ Rẹ

O ní ẹ̀tọ́ kan sí:

- Ìtọ́jú pẹ̀lú ọ̀wọ̀, òtítọ́ àti láìsí ẹlẹ́yàmẹ̀yà;
- Láti jẹ́ kí àlàyé nípa rẹ jẹ́ ìpamọ́ láàrín òṣùwọ̀n òfin àti àwọn ìlànà DSHS;
- Má ṣe jẹ́ ìlòkulò, àìfiyèsí, ìyanjẹ owó, tàbí kí wọ́n kọ̀ ọ́ sílẹ̀. Fún àpejúwè àwọn òfin wọnyí, kànsí: [https://www.dshs.wa.gov/altsa/home-and-community-services/types-and-signs-abuse](https://www.dshs.wa.gov/altsa/home-and-community-services/types-and-signs-abuse). Tí a bá lò ọ tàbí ẹnìkan tí o mọ ní Ìlòkulò, àìfiyèsí tàbí yànjẹ, jọwọ pe DSHS ní Ìpè ọfẹ ní 1-866-(End Harm) / 1-866-363-4276 láti bá òṣìṣẹ kan tí o lè ràn ọ lọwọ sọrọ;
- Kí a tọ́jú ohun ìní rẹ pẹ̀lú ọ̀wọ̀;
- Kí a sọ fún ọ nípa gbogbo àwọn iṣẹ́ tí o le gbà kí o sì yan nípa àwọn iṣẹ́ tí o fẹ́ tàbí tí o kò fẹ́;
- Ṣiṣẹ́ papọ̀ pẹ̀lú òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ láti pinnu ìtọ́jú;
- Kí a má fipá mú ọ láti dáhùn àwọn ìbéèrè tàbí ṣe ohun tí o kò fẹ́ ṣe;
- Kí a wífún ọ ní àfọwọ́kọ ti àwọn ìpinu àṣojú kí o sì gba ẹ̀dà kan ti ètò ìtọ́jú rẹ tàbí ìsọníṣókí ètò àtìlẹ́yìn;
- Bá adarí kan sọ̀rọ̀ tí ìwọ àti òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ kò bá gbà;
- Bèrè gbígbọ́ aṣàkóso kan kódà tí o bá ti ṣe awuyewuye kan;
- Ṣàwuye láìsí ìbẹ̀rù ìpalára kódà tí o bá bèrè ìgbẹ̀jọ́ aṣàkóso kan;
- Baì agbẹjọroÌ sọrọ niìpa piìpe 1-888-201-1014;
- Kọ gbogbo iṣẹ́;
- Jẹ́ kí a pèsè ògbùfọ̀ kan fún ọ lọ́fẹ̀ẹ́ tí o kò bá le sọ tàbí gbọ́ èdè Gẹ̀ẹ́sì pẹ̀lú;
- Yàn, lé tàbí yí olùpèsè akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ kan padà; kí o sì
- Gba àwọn èsì ti àyẹ̀wò àtẹ̀yìnwá rẹ fún èyíkéyìí olùpèsè tí o yàn.

## Àwọn Ojúṣe Rẹ

O ní ojúṣe láti:

- Jẹ́ kí òṣìṣẹ́ ẹjọ́ náà parí àyẹ̀wò rẹ ó kéré jù lọ́dọdún ní ibi tó rọrùn fún ọ;
- Jẹ́ kí òṣìṣẹ́ ẹjọ́ náà wo àyíká ibùgbé rẹ kéré jù lọ́dọdún;
- Fún wa ní ọ̀pọ̀ àlàyé láti parí àyẹ̀wò rẹ;
- Sọ fún òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ tí ẹlòmíràn bá ṣe ìpinu ìṣúná tàbí ìtọ́jú ìlera fún ọ;
- Kópa nínú ìdàgbàsókè ìtọ́jú rẹ tàbí ètò àtìlẹ́yìn, kí o sì buwọ́lùú;
- Ní òye wípé a kò le sanwó fún olùpèsè rẹ fún àwọn iṣẹ́ tàbí wákàtí tí a kò fún ní àṣẹ;
- Yan ìtọ́jú ìlera tìrẹ;
- Yan olùpèsè akọ́ṣẹ́mọṣẹ́;
- Pèsè ibi iṣẹ́ àábò kan;
- Jẹ́ kí àyẹ̀wò àtẹ̀yìnwá olùpèsè rẹ jẹ́ ohun àṣírí;
- Sọ fún òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ tí o bá ní ìṣòro pẹ̀lú olùpèsè rẹ tàbí tí o kò bá gba iye wákàtí tí olùpèsè rẹ sọ;
- Sanwó fún olùpèsè rẹ ní oṣọṣù ti o bá ṣèrànwọ́ sísanwó fún ìtọ́jú rẹ;
- Máṣe wùwà ní ọ̀nà tí yóò fi ẹlòmíràn sínú ewu; àti
- Sọ fún òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ tí àyípadà bá wà nínú:
  - ✓ Ipò ìtọ́jú ìlera rẹ;
  - ✓ Ìrànlọ́wọ́ tí o gbà láti ọ̀dọ̀ ẹbí tàbí àwọn aṣojú mìràn;
  - ✓ Ibi tí o ń gbé; tàbí
  - ✓ Ipò ìṣúná rẹ.



Barcode label

16172

## Àwọn Ojúṣe Òṣìṣẹ́ Ẹjọ́

Ojúṣe òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ ni láti:

- Tójú rẹ pẹ̀lú òtítọ́ àti ọ̀wọ̀;
- Bójútó ìpamọ́ rẹ;
- Wífún ọ ohun tí ALTSA àti DDA le ṣe, tàbí tí wọn kò le ṣe, fún ọ;
- Gba àlàyé láti ọ̀dọ̀ rẹ àti àwọn míràn láti ṣe àyẹ̀wò láti pinnu ipele ìrànlọ́wọ́ rẹ kí wọ́n sì sọ irú àwọn iṣẹ́ tí o le yàn níbẹ̀.
  - ✓ Àyẹ̀wò náà yóò pẹ̀lú àwọn okun rẹ, òdíwọ̀n, ìlépa, àti àwọn ohun tí o fẹ́.
  - ✓ Àyẹ̀wò náà yóò pẹ̀lú ìrànlọ́wọ́ tí o ń gbà tẹ́lẹ̀ tàbí tí o le gbà láti ẹbí tàbí àwọn aṣojú míràn àti bí o ti fẹ́ kí àwọn iṣẹ́ náà ṣe di ṣíṣe;
- Ràn ọ́ lọ́wọ́ láti ṣe ètò ìtọ́jú kan tàbí ètò àtìlẹ́yìn tó kan ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìtọ́jú ara ẹni tó sì kan àwọn ìlépa àdáni, ohun tí o fẹ́, àti àwọn ẹ̀yàn;
- Gba àlàyé láti ọ̀dọ̀ rẹ àti àwọn míràn láti mú kí ètò ìtọ́jú rẹ dójú ìwọ̀n tàbí ètò àtìlẹ́yìn ní ọdọdún tàbí nígbàtí ipò rẹ bá yípadà;
- Fún ọ ní ọ̀pọ̀ àkókò láti pèsè àlàyé tó nílò;
- Yanjú àwọn ìṣòro pẹ̀lú ètò ìtọ́jú rẹ tàbí ètò àtìlẹ́yìn bí wọ́n ti jẹyọ;
- Bọ̀wọ̀ fún àwọn ẹ̀tọ́ rẹ kí o sì pèsè ìrànlọ́wọ́ láti ráyèsí àwọn iṣẹ́ tí o bá ní ìṣòro ọpọlọ, iṣan, òórùn, tàbí àfojúrí; àti
- Ràn ọ́ lọ́wọ́ láti wá olùpèsè akọ́ṣẹ́mọṣẹ́ tí o kò bá le rí ìkan.

## Àwọn Ìtọ́ni Ìjìnlẹ̀

O ní ẹ̀tọ́ láti ní ìtọ́ni ìjìnlẹ̀. Ìtọ́ni ìjìnlẹ̀ le pẹ̀lú ìfẹ́ alàyè tàbí agbára agbẹ́jọ́rò fún ìtọ́jú ìlera. Ìtọ́ni ìjìnlẹ̀ ṣàkópọ̀ àwọn ohun tí o fẹ́ nípa ìtọ́jú ìlera àti/tàbí ọpọlọ, èyí pẹ̀lú ẹ̀tọ́ láti gbà tàbí kọ ìtọ́jú ìlera, ọpọlọ, tàbí iṣẹ́ abẹ, nígbàtí o ní ọpọlọ láti ṣe àwọn ìpinnu náà. O le gba ìtọ́ni ìjìnlẹ̀ rẹ padà nigbàkugbà.

## Iṣẹ́ Ìforúkọsílẹ̀ Olùdìbò

Òfin Ìforúkọsílẹ̀ Orílẹ̀-èdè ti 1993 nílò kí gbogbo orílẹ̀-èdè láti pèsè ìrànlọ́wọ́ ìforúkọsílẹ̀ olùdìbò nípasẹ̀ ibi-iṣẹ́ ìrànlọ́wọ́ gbogbogbò wọn. Bíbèrè láti forúkọsílẹ̀ tàbí kọ̀ láti forúkọsílẹ̀ láti dìbò kò ní kan àwọn iṣẹ́ tàbí iye àwọn ànfàní tí aṣojú yóò pèsè fún ọ. Tí o bá nílò ìrànlọ́wọ́ láti kún fọ́ọ̀mù ìforúkọsílẹ̀ olùdìbò, a ó ràn ọ́ lọ́wọ́. Ìpinnu rẹ láti forúkọsílẹ̀ tàbí láti kọ̀ láti forúkọsílẹ̀ ni a ó fipamọ́ a ó sì lòó fún èrèdí ìforúkọsílẹ̀ olùdìbò nìkan. Tí o bá gbàgbọ́ wípé ẹnìkan ti kọlù ẹ̀tọ́ rẹ láti forúkọsílẹ̀ tàbí láti kọ̀ láti forúkọsílẹ̀ láti dìbò, ẹ̀tọ́ rẹ sí ìpamọ́ láti pinnu bóyá láti forúkọsílẹ̀ tàbí tàbí láti bèrè láti forúkọsílẹ̀ láti dìbò, tàbí ẹ̀tọ́ rẹ láti yan ẹgbẹ́ òṣèlú tìrẹ tàbí irúfẹ́òṣèlú míràn, o le pẹjọ́ awuyewuye pẹ̀lú:

Washington State Elections Office
PO Box 40229
Olympia WA 98504-0229
1-800-448-4881

## Ìbuwọ́lù Rẹ

Buwọ́lù lórí ìlà nísàlẹ̀ tí o bá lóye àwọn ẹ̀tọ́ àti ojúṣe rẹ tí o sì lóye àwọn ojúṣe òṣìṣẹ́ ẹjọ́ rẹ.

________________________________________
ÌBUWỌ́LÙ ONÍBÀÁRÀ

________________________________________
DÉÈTÌ

________________________________________
ÌBUWỌ́LÙ AṢOJÚ ÒFIN

________________________________________
DÉÈTÌ

Àkíyèsí fún àwọn oníbàárà àti òṣìṣẹ́ (Àkọlé VI àti VII) Àwọn Iṣẹ́ Ìlera àti Ìgbàlódé ti Ẹ̀ka Iṣẹ́ Ìpínlẹ̀ Washington jẹ́ agbaniṣíṣẹ́ láì ṣojúṣàájú kò sì ṣe ẹlẹ́yamẹ̀yà ní abala iṣẹ́ kankan, àwọn ètò tàbí àwọn iṣẹ́ lórí ojó-orí, akọ tàbí abo, ìṣe ìfẹ́, ọkùnrin tàbí obìnrin, ìdámọ̀/àfihàn ọkùnrin tàbí obìnrin, ipò ìgbéyàwó, ẹ̀yà, orírun, àwọ̀, orílẹ̀-èdè ìbí, ẹ̀sìn tàbí ohun ìgbàgbọ́, ẹgbẹ́ òṣèlù, ipò ọmọ ogun, jagunjagun tí a fisílẹ̀ pẹ̀lú ọlá, Ìgba Vietnam, túká láìpẹ́ tàbí ipò jagunjagun alábòó míràn, ìfarahàn èyíkéyìí ìgbóòrùn, ọpọlọ, abarapá àfojúrí tàbí ìlò ajá tí a kọ́ fún itọ́ni tàbí iṣẹ́ ẹranko nípa ènìyàn tó jẹ́ abarapá, ìsanwó kannáà tàbí àlàyé gbogbogbò.

**Àwọn ẹtọ àti Àwọn ojúṣe rẹ Nígbà tí O Gba Àwọn Iṣẹ tí a fúnni nípasẹ**
**Ìṣàkóso Àtìlẹyìn Ìgbà pípẹ àti ọjọ ogbó àti Ìṣàkóso ÀÌléra Ìdàgbàsókè**

ÀWỌN ÌTỌNI

1. Fún oníbàárà ní fọ̀ọ̀mù yìí nígbàtí o bá parí àyẹ̀wò ÌTỌ́JÚ kí o sì ṣàtúnwò ètò ìtọ́jú tàbí ètò àtìlẹ́yìn. Tí oníbàárà bá ti ń gba àwọn iṣẹ́ tí kò sì buwọ́lu ẹ̀yà fọ̀ọ̀mù yìí tẹ́lẹ̀, fún oníbàárà ni fọ̀ọ̀mù náà ní àyẹ̀wò tókàn. Ṣàtúnwò fọ̀ọ̀mù náà pẹ̀lú oníbàárà láti dáhùn èyíkéyìí ìbéèrè nípa àwọn ẹ̀tọ́ àti ojúṣe oníbàárà.
2. Jẹ́ kí oníbàárà tàbí aṣojú oníbàárà buwọ́lu ẹ̀dà méjì ti fọ̀ọ̀mù náà láti ṣàfihàn òye rẹ̀ nípa ti ẹ̀tọ́ àti ojúṣe ti oníbàárà nígbàtí o ń gba àwọn iṣẹ́ èyítí Ìṣàkóso Àtìlẹ́yìn Arúgbó àti Ọlọ́jọ́ Pípẹ́ àti Ìṣàkóso Ìdàgbà Abarapá.
3. Ṣe ẹ̀dà kan nínú ìwé àfọwọ́kàn tàbí Ìlànà-ètò Ìṣàkóso Àkọsílẹ̀ (DMS) kí o sì fi ẹ̀dà kejì fún oníbàárà.